OWE

Ẹniti yio ku iku ẹrẹ ọwọ ara rẹ ni yio fi fa a.

# Irohin Yoruba

VOL IX No 460 MONDAY MAY 3, 1954 KOBO KAN (1d)

E ma a polowo oja nyin sinu iwe Irohin Yoruba

# Awon Olori Oselu Meta Pade



DỌKITA Nnamidi Azikiwe, Olori Ẹgbẹ N.C.-N.C. ati alakoso Igbimọ Aṣofin Ijọba Ila-Orun Nigeria (Ibo) Sardauna Sokoto, Olori Ẹgbẹ Northern People's Congress ati Alakoso Igbimọ Aṣofin Ijọba Iha Ariwa Nigeria (Hausa) ati Ọlọla Ọbafẹmi Awolọwọ Olori Ẹgbẹ Action Group ati Alakoso Igbimọ Aṣofin Iwọ-Orun Nigeria (Yoruba) pade ni Zaria.

Sardauna Sokoto ni o pe awọn Ọlọla Awolọwọ ati Azikiwe wa si Zaria fun ẹyẹ iṣile Ile Ẹkọ awọn oniṣẹ Ijọba (Institute of Administration) ti nwọn ṣẹṣẹ kọ sibẹ, ti nwọn si ṣe ẹyẹ iṣile na ni ọjọ kẹrinlelogun oṣu yi.

Ẹyẹ iṣile na dun o larinrin, Gomina Nigeria, Ọlọla John Macpherson paapa ni o ṣi Ile Ẹkọ pataki na, Ọba Eko Alaiyeluwa Adeniji Adele Keji wa ninu awọn ọlọla ti o lọ bukun aṣeyẹ na.

## Oloye Akinyele Di Olori Adajo Kotu Ibile

IBADAN—Ni ọjọ Ru ti iṣe ọjọ kọkanlelogun oṣu kẹrin ọdun yi ni ọpọ ogunlọgọ awọn enia pataki pataki kakiri abẹ Ijọba Iwọ-Orun Nigeria pe ṣọṣọ si gbọngan apejọ Mapo Ibadan lati ri eto aṣeyẹ awọn enia mejọ ti nwọn fi jẹ oye Onidajọ kotu Ibilẹ Ibadan ati awọn ọgbọn oluranlọwọ [assessors] wọn eyiti nwọn ṣe lori eto iṣelu titun.

Oloye I.B.A. Akinyele ni Olori awọn Adajọ na, gbogbo awọn adajọ na ni nwọn wọ agbada nla-ti ni ọkan-ko-jọkan de-lẹ, Ajẹlẹ Agba Ibadan ati Ọlọla Ọbafẹmi Awolọwọ, Alakoso Igbimọ Aṣofin Ijọba Iwọ-Orun Nigeria ni nwọn fi awọn iwe-aṣẹ idajọ le gbogbo wọn lọwọ.

Ọgbẹni Awolọwọ yin Olubadan ati awọn Agbagba Ijoye ati Igbimọ ajọ ti ilu Ibadan fun akiyesi ti nwọn ni eyiti o mu wọn ṣe pe nwọn nfẹ ki nwọn tun awọn eto Kotu Ibilẹ Ibadan ṣe ati pe nwọn si ṣi Oloye Akinyẹle Olori awọn Adajọ na leti pe ki o ri pe nwọn nṣiṣẹ wọn pẹlu ododo, o si sọ bi awọn adajọ tuntun na ti jẹ ọmọwe ati ọmọluwabi ati bi lakayẹ wọn si ti ṣe pe pupọ si, o si gbadura fun wọn. Ninu ọrọ rẹ o ni bi nwọn ba ti nṣiṣẹ wọn pẹlu ododo Ijọba Iwọ-orun Nigeria yio ma a wa pẹlu wọn.

Lẹhinti o sọ ohun ti eto tuntun nfẹ lati o ṣe ikilọ pupọ fun awọn onidajọ titun na ati awọn oluranlọwọ (Assessors) wọn pe ki nwọn ma ṣe jẹ ki awọn iwa kikiwa ti o ti wa tẹlẹtẹlẹ ri ninu awọn kotu ibilẹ ti nwọn yio ma a dajọ yi tun ṣẹlẹ mọ.

Awọn onidajọ tuntun ti nwọn ṣẹṣẹ yan na ni Oloye I.B.A. Akinyẹle, O.B.E., Adajọ agba, Oloye Akinpelu Obisesan O.B.E., Oloye D.T. Akinbiyi M.H.A., Alhaji S.B. Saiami, Mogaji Oshunware, Oloye J.L. Ogunsọla ati Oloye O.A. Adetoun. Ki Ọlọrun jẹ Amọna awọn Adajọ titun na, ki O si fun wọn ni ẹmi gigun ati alafia.

## Yesufu Adeniji fo wa s'Eko

EKO—Ni ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ogunjọ oṣu kẹrin ọdun yi [20/4/54] ni Ọgbẹni Yesufu Adeniji, Alaga Ẹgbẹ Ogbomọshọ Parapọ Oke Okun ba ọkọ ofurufu fo wa si Eko lati Accra, Gold Coast ti iṣe ibujoko owo rẹ.

Ọgbẹni Yesufu Adeniji jẹ onisowo Pataki ni ilu Accra, Gold Coast o si tun jẹ ọkan pataki ninu awọn Onibara Iwe Irohin Yoruba ni Oke Okun, ohun pataki ti o ba wa si Eko ni lati wa ra awọn ọja pataki pataki ti i ma a saaba ra lati Nigeria lọ ta ni Oke Okun.

Ni ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kẹtalelogun oṣu na ni o wa ṣe ibẹwo Olotu Irohin Yoruba, inu Olotu si dun lati ri i nitori eyi ni akoko ti nwọn a kọ f'oju kan ara wọn lati igbati nwọn ti ngburo ara wọn bi olubaṣowopọ nipa tita ati rira Iwe Irohin Yoruba.

Lẹhin ti nwọn jijọ sọ asọye pọ tan ni Olotu ba

Wo oju ewe kerin

## Oladipo Godo Tu Awon Ole Fo

IDI ọrọ na ni pe ni ọjọ kẹsan oṣu kejila ọdun ti o kọja yi ni Sidi Yaro, agbawo [Steward-boy] awọn Oyinbo Onisowo A. G. Leventis Ebute Meta pẹlu enikan lọ ko ile awọn Ọgbẹni Francis Merron ati James Toolan awọn Oyinbo ti nṣiṣẹ ni "Bank of British West Africa" ni ile wọn ni Ikoyi, awọn inkan elo ti nwọn ji ko na to oni-pọnun mejidilọgọrun ṣile mejọ (£78:8:0d).

Nwọn wa lọ pe Ọgbẹni Mexi Ladipọ Godo, onimọto (Taxi Driver) lati ba wọn ko lọ si ile awọn, nighati Ladipọ woye pe ẹru ole ni nwọn pe on si, bi o kanran ki o gbe wọn lọ si ile wọn, ṣabu Ọlọpa [Police Station] ni o wa wọn lọ pẹlu ẹru wọn.

Bayi ni Ọlọpa ṣe mu Sidi Yaro, ṣugbọn enikeji rẹ salọ. Ni ọjọ kerinlelogun oṣu kerin ọdun yi ni nwọn ṣe ẹjọ rẹ ni Kotu Gantan (Lagos Assizes) Adajọ Agba Ọgbẹni Fredrick E Johnson ni i pe Sidi Yaro jebi ẹsun ole jija na o si sọ si ẹwọn ọdun mẹta oniṣẹ aṣekara.

Adajọ na sọrọ apọnle Ladipọ pupọ o si ni ki ẹga awọn ọlọpa (Inspector of Police) ya a sọtọ larin awọn onimoto [Taxi Driver] fun iwa rere, a dara ti gbogbo awọn onimoto (Drivers) ba le ma a se afarawe iwa Ladipọ Godo.



MEXI LADIPỌ GODO

## Gbajumo N.C.N.C. Marun Di Action Group Ni Ilesha

LAIPẸ yi ni awọn ogunna gbongbo Ẹgbẹ N.C.N.C. Ilesha marun pada di ọmọ ẹgbẹ Action Group ni ilu Ilesha. Awọn ni Ọgbẹni S. A. Ọlatunji enia iṣe igbakeji akọwe ẹgbẹ Imale ni gbogbo Nigeria, Ọgbẹni Isaiah Ọmọniyi eniti nṣe iṣẹ aṣọ-riran, Ọgbẹni Isaiah Aregbesọla, Joseph Ayọdele Oshungbure, Agboola Awe eniti nṣe oga iṣẹ Awes Photo Ilesha.

Gbogbo awọn so wipe awọn ti ara mọ ẹgbẹ eyiti yio ṣe ọmọ ẹdẹ wa lanfani, nwọn si fi ara mọ Action Group lati ọjọ na lọ.

E Ma a Ka Iwe Irohin Yoruba

Nigbagbogbo Fun Irohin Aladun

PR-GRESS

O! ARE U MISSING

16 hours of it for less than

3D A DAY---GET REDIFF-SION

